# Gbẹddẹ ti nlepa ilọsiwaju Ijumu lati ọjọ pipẹ

*(Lati ọwọ S. I. Ibidun, Aiyetoro, Gbẹddẹ)*

**MO fẹ fi oye diẹ ye Ọgbẹni Michael Aṣaju ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti nwọn ṣẹṣẹ de ni akoko yi wipe, awọn ni yio fi kumọ irin pa gbogbo Ijumu pọ ni ọjọ kanṣoṣo, ṣugbọn oye ko ye wọn wipe "Ile ni a ti nko ẹṣọ rode."**

Mo fẹ ki gbogbo wọn patapata fẹti silẹ ki nwọn gbọ nipa gẹgẹbi ilu Gbẹddẹ ti ṣe nlepa ilọsiwaju ilẹ Ijumu ati ọjọ pipẹ sẹhin wa.

**KOTU IJỌBA IBILẸ**

Lẹhin ọdun 1920, ti Eni-Qwọ Ologbe Oloye Ẹlẹta Ayẹni, ti a kọkọ mọ gẹgẹbi Olu Ijumu Kini, On ni o gba Kotu Ijọba Ibilẹ fun ilẹ Ijumu, o si ṣe eto pe ki awọn enia ilẹ Ijumu le ma a pa ara wọn pọ kuro ninu awọn Ileto keekeeke ti nwọn ti wa tẹleri ni akoko igbana.

On kanna ti o mu imọran yi wa na ni o si kọkọ fi apẹẹrẹ rere lelẹ nipa pe, o ṣi kuro ni ileto ti ara rẹ paapa ti a npe ni INDO wa si Aiyede lẹba ODOKORO.

Awọn ileto ti o ṣipo kuro ni aye wọn wa joko pẹlu Ọba rere yi ni Aiyede niwọnyi:—Ọyẹh, Jangandi Ọka ati Ilarin. Nitori iwa rere ti Ọba yi ni, ati pe, o ti ṣe iṣẹ Ijọba kakiri ni ẹhin odi, o si ri iriri orişiṣiriṣi ninu eyiti o le fi ṣe ẹkọ lati fi tọ awọn ara ilu sọna.

**IMỌRAN OLOYE AYẸNI**

Oloye Ẹlẹta Ayẹni yi a ma a fi igba gbogbo sọ fun awọn enia Gbẹddẹ pe, bi awọn ara ilu Indọ ba fi dandan le e wipe ninu ilu kekere yi ni awọn yio ma a gbe titi lai, ilu awọn na ko ni tete ni ilọsiwaju, afi bi awọn ba le ṣi kuro nibẹ ki awọn si lọ tẹdo si ilẹ ibomiran.

Mo si ni igbagbọ wipe bakanna ni o tun ngba awọn ara ilu Ijumu-Arin ati Ogidi ni imọran nigbana pẹlu.

Lati igbana ni Gbẹddẹ ti ngbiyanju lati ni irẹpọ larin ara wọn nitori ki orilẹ-ede Ijumu ba le tete ni igbega ati ilọsiwaju.

**ERO NIPA APAPỌ**

Lẹhin iku Ẹlẹta Ayẹni, awọn ara ilu Gbẹddẹ ko mẹnuko lori ero bi awọn yio ti ṣe papọ pẹlu awọn ileto yoku ki awọn si ṣi kuro ninu ileto kekere na gẹgẹbi ilana ti Ẹlẹta na ti fi lelẹ ki o to ku.

Nipa bẹ ẹ, awọn ileto nlanla mẹsan, Aggọ, Akurẹ, Esee, Ọfẹdẹ, Agbara, Okeleti, Igga, Ilu-Ẹshọ ati Eguru ni o lọ papọ mọ ilu Aiyegunlẹ ti o tẹle ilu Aiyetoro nipa titobi ati ọpọ enia nibẹ ni Olugbẹdẹ wa loni.

Lẹhin na, ẹ tun fi ojuinu wo ilu Aiyetoro ti o jẹ ilu ti o tobi ju gbogbo awọn ilu ti wa ni ilẹ Ijumu lọ. Ilu Aiyetoro na ni o tun jẹ gbakeji si ilu Kabba nipa titobi ati ọpọ enia ninu gbogbo awọn ilu ti o wa yika ẹkun Kabba, ko si si ileto kan ni Gbẹddẹ ati yika gbogbo agbegbe rẹ ti ko si ninu ilu Aiyetoro na loni yi.

Nigbati Gbẹddẹ bẹrẹ eto ipapọ yi, ki iṣe wipe ko si awọn enia ti o le lo agbara lati pa awọn enia ilẹ Gbẹddẹ pọ sibi kanṣoṣo nigbana, ṣugbọn nwọn mọ wipe: "A ki i kanju mọ ori".

Nitorina ni nwọn ṣe fi wọn lara balẹ pe ki nwọn fi ẹsọ-ẹsọ ma a ṣe ipapọ na pẹlu ara wọn letoleto ati ni idẹra. Nwọn "ko si lo iru agbara ati aṣẹ kan-



OLUJUMU IJUMU

* * *

npa ti awọn Ẹgbẹ IPU fẹ lo yi. Nwọn mọ wipe bi awọn ba lo o bẹẹ, yio mu inira ati ibajẹ wa, dipo pe ki o rọrun, ki o si dara.

Nitorina, mo fẹ ki o ye Ọmọ-ọba M. Aṣaju ati awọn ẹgbẹ rẹ, IPU wipe, ohun ti o mu ọgbọn dani ni ọrọ ti mo sọ ni oke iwe yi, ṣugbọn bi nwọn ba nro wipe awọn le fi ipa mu gbogbo ilu Ijumu lati papọ ni ọjọ kanṣoṣo, ohun ti ko mu ọgbọn dani patapata gba a a ni.

**IPAPỌ KO ṢORO**

Bi Gbẹddẹ ba fẹ ni ilu kan ti Afin Ọba wọn yio wa ninu rẹ, ko le ṣoro fun wa rara nitori idi meji pataki, ekini ni pe: ọkanṣoṣo ni Gbẹddẹ jẹ lati ibẹrẹ, eto oye kanṣoṣo ni a si fi nṣe ilu Gbẹddẹ.

Ẹkeji si ni pe: Gbẹddẹ ti mọ ara wọn ni ọkanṣoṣo latilẹwa, nitorina, nwọn a ma a wa ọna lati ba ara wọn ṣe papọ lati ẹhin wa gẹgẹbi itan ati alaye ti mo ti ṣe ni ibẹrẹ nipa awọn eto iṣipopada ti nwọn jijọ nṣe lati ẹhin wa fun ilọsiwaju ilẹ Ijumu ti nwọn nlepa.

Ilu kanṣoṣo ti Gbẹddẹ ni gẹgẹbi agbajọ ilẹ Gbẹddẹ na ni Aiyetoro Gbẹddẹ, o si ti ni awọn aṣoju tirẹ nibẹ pẹlu. Mo fẹ bere lọwọ aburo mi Ọmọ-ọba Aṣaju pe, njẹ ohun ti mo wi wọnyi ri bẹ ẹ ni ilẹ Ijumu? Ko ma ri bẹ ẹ rara o!

**ADDE ATI IYARA**

Idi ti mo fi mọ wipe ko ri bẹ ẹ pe orişirisi. Awọn idi na si ni pe, ilu Adde ni o dagba ju ni ilẹ Ijumu, ilu Iyara n'o si tẹle gẹgẹbi itan abalaiye ti a gbọ nipa wọn. Ṣugbọn mo fẹ bere, njẹ nwọn ha jẹ fi ilu Adde na ṣe agba?

Ko ha nṣe wipe olukaluku ni o ni eto oye tirẹ ti o fi nṣe ilu? Njẹ, ẹ le fi agba fun ẹnikan de aye pe ki o ni ẹtọ iṣipopada gẹgẹbi ti Gbẹddẹ, tabi ki ẹ ni ilu nla kan gẹgẹbi ti Gbẹddẹ ni Aiyetoro? Ilu Iyara ti ẹ ni na ni ẹ nfẹ ki o jẹ Olu-ilu fun ilẹ Ijumu. Njẹ ilu Ikoyi ati Ifẹ ti o wa ni ibuso mẹta si Iyara jẹ ṣi wa si Iyara? tabi ilu Ẹgbẹda-Ẹgba jẹ ṣilọ si Ogidi ti o tun dabi agba ilu fun Apapọ awọn ileto Ogidi (Ogiddi Group?)

—Ẹnyin ti ẹ sọ wipe ẹ o pa Ijumu pọ ni ọjọ kanṣoṣo na ni ilẹ nyin kuku ri bi o ti ri yẹn, ti ẹ ko si ti i ri nkankan ṣe si i!

Iwọ Ọmọ-ọba Aṣaju onimọran, inu mi iba dun pupọ bi o ba ṣe wipe o le mọ wipe, "ile ni a ti nko ẹṣọ r'ode". Ọmọ Ijumu-Arin ni nyin. Mo fẹ ki ẹ lo ọgbọn tabi ipa ti iwọ ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pinnu lati lo fi pa gbogbo Ijumu pọ lẹkanṣoṣo. Ẹ lo ọgbọn na fun ipapọ ilu Ijumu-Arin wayi o, ọmọ ibẹ na ni ẹ kuku nṣe.

Mo fẹ ki o ye nyin gbangba wipe, Gbẹddẹ ti ni eto ilọsiwaju fun ipapọ ilẹ Ijumu, ti nwọn si ti nlepa rẹ lati ọjọ pipẹ ki iwọ ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ to de.

(Wo oju ewe kẹwa)

Mama fun mi ni




AMAMA ni ojojumọ

AMAMA

O NJẸKI NGNI AGBARA ATI ILERA

NI NAIJIRIA NI A TI ṢE AMAMA

AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD, P. M. B. 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—E ku aro Olotu, se mo ba lalaafia re?
OLOTU—A dupe lowo Olorun.

[illegible]


ALAPARA IBADAN

[illegible]


## Ara-hibun, ara jijoni ati ara-gigenijẹ ti AWỌ-ARA TI KO DARA




[illegible]

NIXODERM




# EKO AKETE

## (Lati ọwọ ọmọ Onilẹ)

[illegible]

## ỌRAN ỌJA

[illegible]

## Animashaun tako awọn Alhadji Eko.

[illegible]

## AWỌN ỌMỌ ILE IWE KABBA KO RI OMI MU

KABBA

[illegible]



[illegible]

## Akede Ọna Igbala

# Omi iye na wa fun ọ lọfẹ

[illegible]

### KINI OMI IYE JE

[illegible]

### IYE AINIPEKUN

[illegible]



[illegible]


Ẹ ma a ka Iwe
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun irohin aladun



# DA ẸHIN-DIDUN RE DURO



nipa titete mojuto awọn ẹree inu ati apo-itọ re
lo
DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

LAKUREGBE,
ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN
ati, Awọn IYỌNU APO-ITỌ

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills



Ihin-rere fun
## AWỌN ATẸWE

| | | |
|---|---|---|
| WHITE BANK | 16½" x 21") 17" x 27") 20" x 30") | 45 grams |
| M.F. WHITE BOND PAPER | 20" x 30") 45 17" x 27") grams | |

Awọn paali VANGUARD BOARDS
26½" x 35"

OKUNỌLA BROTHERS
LAGOS.

# KADARA ẸDA (15)

(Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)

NIGBA pupọ ni igbesi aiye ẹda, a ma a dabi ẹnipe okunkun ti o ṣu bo ni lagbara pupọ to bẹẹ ti ko tun si ireti mọ fun imọlẹ. Eyi a ma a mu ki ọpọlọpọ enia gbagbe ara wọn ati isopọ arin wọn ati Ẹlẹda wọn. Nwọn a si yapa kuro ni gbogbo ọna ti o fi ọgbọn han, nwọn a sọ ara wọn di alawọṣe, keferi, iranṣẹ eṣu ati ọta Ọlọrun-ọta enia.

Wayi o, ninu orişirişi ọna ti enia ma a ngba lati bo ninu iṣoro tabi lati jẹ ohun ti a fẹ jẹ, a ma a npa ara wa lara nipa ọna miran, a npa ẹmi wa lara nipa ọna miran, a si npa awọn ẹda miran lara nipa ọna miran pẹlu.

## IGBA IṢORO

**Şugbọn eyiti o ngmu enia pa ẹmi rẹ lara julọ ninu aşişe awa ẹda ni pe ki enia gba ẹmi ara rẹ funra rẹ lakoko iṣoro.**

O ma a njẹ ohun ibanujẹ ati ikaanu fun mi ni gbogbo igba ti mo ba ka a ninu iwe irohin wipe enia kan so ara rẹ rọ, tabi o yinbọnjẹ, tabi gbe majele jẹ lati gba ẹmi ara rẹ lẹhin ti o ba ti ro gbogbo rẹ pin.

Ohun ti o ya ni lẹnu julọ ni wipe laarin iru awọn ti o nbinu fi opin si ẹmi ara wọn bayi ni a ri awọn enia pataki-pataki ati awọn omowe ati ọlọla. Bakanna ni a si ri awọn olupọnju ati oşişẹ enia.

## ẸṢẸ TO GA JULỌ

Şugbọn eyiowu ki o jẹ, o dabi ẹnipe ẹṣẹ ti o ga de opin ni ki enia gba ẹmi ara rẹ nitori Iṣoro ile aiye yi.

A nilati ma a ranti nigbagbogbo pe ohun iyebiye ti a ko le fi owo ra ni ẹmi wa jẹ, bẹẹni a ko le sọ bi o ṣe de inu wa gẹgẹbi a ko ti le sọ bi awa paapa ṣe wa, ati jade ẹmi kuro lara wa ki i si şe ohun ti a le fi şere.

Bi a ba şakiyesi ohun gbogbo daradara, a o ri i wipe bi a ti npọ si i ni orilẹ ede, bẹni oju tubọ nla si i, bẹni iṣẹ iyanu ẹkọ ijinlẹ (Science) tubọ npọ si i, a si le fikun un pe ẹda enia tubọ njinna si Ọlọrun rẹ, eşu si tubọ ngba ọkan ọmọ enia.

Bi a ba si fi oju ẹmi wo orişirişi ohun gbogbo ti o nşẹlẹ kakiri agbaiye loni, yio ma a ya wa lẹnu bi ẹnikẹni mbẹ laiye yi ti yio ri Ijọba ọrun wọ!

## ORIŞIRIŞI IPỌNJU

Dajudaju a ko le jare Ẹlẹda wa fun fi fi ọwọ ara wa pa ara wa nigba ipọnju tabi ijiya. A ko tilẹ ni ẹnu ti a le fi ba A ro ẹjọ. Lootọ ki enia kan to pinnu lati gba ẹmi ara rẹ, yio ti ro orişirişi iya ti o njẹ ẹ l'aini idi.

Boya aisan kan l'o di mọ ọ ti ko pa a bẹẹni ko si san; boya ipọnju airişe tabi aikoriowoto ni idaamu rẹ;



M. A. AKINBỌADE

* * *

boya nşe ni ko ri ọmọ bi, boya kẹ nşe ni enia kan ti o mọ aşiri rẹ da a.

Ah! iwọ arakunrin ati arabinrin mi, jẹki nsọ fun ọ pe kosi arun kan laiye yi ti Ọlọrun ko le wosan. Mo gbagbọ wipe Ọlọrun ki işe ohun kan l'ainidi, mo si gbagbọ wipe bi enia kan tilẹ jiya titi ti o fi jade ni aiye yi, Ẹlẹda ko şai mọ ọna ti yio gba fi ọrọ di i.

Şugbọn gẹgẹbi irin ajo wa ni ile aiye yi, aseko ni ohun gbogbo. Mo gba wipe ẹda ti gbiyanju nipa imọ ijinlẹ lati ke akoko kuru nipa mọto, reluwe ati ọkọ ofurufu ati nipa orişirişi ọna fifi iwe ati ọrọ ranşẹ si ilu okeere.

Şugbọn sibẹsibẹ koi ti şee şe lati ke aseko ti ẹda kan yio ni ohun ti o fẹ ni tabi jẹ ohun ti o fẹ jẹ kuru.

Lati binu gba ẹmi ara ẹni dabi enia ti ebi npa ti o wa lọ jale ni oju gbangba lati le bọ ninu iya ebi na. Njẹ ajẹkun iya kọ ni yio jẹ?

Awọn ti o ni ohun ti o gbe yio jẹ ẹ niya ọwọ wọn ki nwọn to fa a le Ijọba lọwọ fun iya ti o ga ju bẹ lọ, ko si tilẹ ni ri aye jẹ onjẹ na ti o jale fun.

## ITIJU IBANUJẸ

Ẹniti o ba binu gba ẹmi ara rẹ nitori iṣoro yio da itiju ati ibanujẹ silẹ fun awọn enia rẹ, iya ti yio si jẹ yio pọ pupọ ju eyiti o sa fun lọ.

Botiwu ki işoro kan tobi to, o yẹ ki a ma a sunmọ Ọlọrun, ki a si ma a bere amọran awọn diẹ ti a ba le fi inu wa han.

Nipa orişirişi ọrọ işiri ati amọran ati nipa iranlọwọ miran gbogbo, ibanujẹ ko ni ri aye fi idi mulẹ lọkan enia.

Nigbati akoko ba si to Olọdumare A ma a ko ẹni yọ.

**ALAFIA FUN NYIN.**

# ITAN OŞUPA

(Lati oju ewe kẹrin)

ibanujẹ aiya ni ọkan fi nrẹwẹsi, eyi gan an ni o fa a ti ọran na ko si kuro ni ọkan iya Oşupa to bẹ ẹ ti on na fi ku lẹhin ọdun kan ati oşu kan. Lẹhin iku ọkọ rẹ gbogbo rẹ wa di rudurudu.

Nisisiyi, "Ọkẹrẹ gun ori iroko oju ọdẹ da", ni ọran yi jẹ fun Oşupa, inu rẹ si bajẹ gidigidi nitori ko si alabaro ati alafẹhinti fun un mọ, gbogbo wọn ni iku ti mu lọ.

A! iya Oşupa ku, wura Oşupa bajẹ baba Oşunpa ku jigi rẹ si ti wọ inu alagbalugbu omi-okun lọ. Ẹbẹ ni a bẹ Edumare, ki o maşe fi ohun buburu şe ẹda mọ, ki a gbo bi orogbo ki a di agba atata, ki afọn wa maşe wọ ni aigbo, ki a maşe fi ọmọ wa silẹ ni rewerewe.

(KOI TI PARI O)

Nikehin wayi

abẹ infarungbọn to mu julọ




Ọbe Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD · LAGOS · ABA · KANO

# 'National Bank' di ti Ipinlẹ Iwọ-Orun




Aworan yi ni ti Ile-iṣẹ 'National Bank' l'Eko

* * *

(Lati oju ewe kini)

ing Board" Ipinlẹ Iwọ-Orun. Eyini ni pe 'National Bank' ti di ti awọn enia Ipinlẹ Iwọ-Orun.

**KO SI IYATỌ**

"Gbigba ti Ijọba mi gba Banki yi lati ọwọ awọn Aṣoju rẹ ko yatọ si bi Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ti gba "African Continental Bank" ati bi Ijọba Ipinle Ariwa ti ṣe da "Bank of the North" silẹ.

"A ti ni Banki tiwa nisisiyi, eyiti yio tubọ kọju mọ iṣẹ awọn agbẹ ati awọn oniṣowo keekeeke yika gbogbo Naijiria. Bi a si ti gba Banki yi, a nilati tubọ mura si eto atunṣe itankalẹ rẹ kikankikan.

"Mo kan-saara si awọn oludasilẹ Banki na bi Dọkita Akinọla Maja, Ọlọla T. Adebayọ Doherty, ọkan ninu Igbimọ awọn Agba-oṣelu Apapọ Ijọba Naijiria ati Alhaji S. O. Gbadamọsi.

**ALAKOSO AGBA**

Mo yin wọn fun iforiti ati ifarada wọn nitoripe nwọn ti ṣe iṣẹ akọni ati olulana wọn pẹlu igboiya

"Igbagbogbo ni a o si ma a ranti orukọ wọn fun iṣẹ ribiribi ti nwọn ti ṣe fun ilu yi, lati ibẹrẹ kekere ni nwọn si ti sọ Banki yi di nla, a si dupẹ lọwọ awọn ọjọgbọn ati oloye enia ti nwọn ti nṣe alamojuto iṣẹ yi latẹhinwa."

Oloye Akintọla si tun sọ wipe, on ro wipe yio dunmọ awọn ọlọla Igbimọ ninu lati gbọ wipe, Ọgbẹni S. L. Durosarọ ni awọn Igbimọ Alakoso iṣẹ na yan ni Alakoso-agba fun Banki na gẹgẹbi iṣiṣẹ kini ninu eto ti on ti sọ na.

O nį oye ti Ọgbẹni Durosarọ ti ni nigbati o nṣiṣẹ fun Ẹgbẹ Marketing Board yio ran an lọwọ lati ṣ'akoso iṣẹ Banki na dada, atipe, on ni ero wipe Ajọ Igbimọ yi yio ki i ku orire ninu iṣẹ titun ti o gba yi. Lẹhin tį Ijọba on ba si ti gba imọran lọdọ Banki nla "Central Bank", awọn yio yan awọn ọjọgbọn iṣẹ Banki sibẹ.

Oloye Akintọla si sọ ninu ipari ọrọ rẹ pe: "Lotitọ, eto atijọ ti fi aye silẹ fun titun, ṣugbọn nipa amojuto awọn Alakoso iṣẹ Banki na, yio tun ma a tẹle awọn eto ti awọn oludasilẹ rẹ tį ṣe latilẹ, eyini nį pe, yio ma a ya awọn oniṣowo lowo deede, on ni yio si ma a ṣe aṣiwaju ninu eto idagbasoke owo ni Naijiria.


## Gbogbo ẹbi ko ni fi ẹsẹ kan ilẹ-tutu



. . . ni igba ojo! Wa si Ṣọbu BATA ki o wa ra bata-ojo fun awọn ọmọ rẹ ati aya rẹ.

Bata awọn ọmọde
Iwọn ẹsẹ 4 si 9
jẹ 12s. 6d.
Iru bata 85.
Iwọn-ẹsẹ 6 si
9 jẹ 15s. ati
10 si 2 jẹ 17s. 6d.
Iru bata 45.

Bata-ojo fun baba ati iya pẹlu. Nwọn wa ni iwọn-ẹsẹ 6 si 11 fun ọkunrin ti owo rẹ jẹ 10s. ati 3 si 8 fun obirin ti owo rẹ jẹ 9s. 6d.



Iru bata 609

**Bata**

AKANBATA FUN GBOGBO AGBAIYE
81/87 Broad Street, Lagos
Ati ni Ẹkọ Ile-iṣẹ wọn





## O KURO NINU ERE-IJE ?

# Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri !

Pẹlu

## ANDREWS LIVER SALT



O ko le jẹ igbadun aiye nigbati ara ba nkun ọ, agbẹdu nro ọ, ara ndun ọ o si nkan ọ yipo ara. Ma a mu Andrews Liver Salt lojojumọ ki o si di alagbara gẹgẹbi Ẹrọ! Idan Andrews Liver Salt ti o nho suṣu yio jẹki o ni alafia ni gbogbo ọjọ. Bere fun Andrews ki o si taji loju oorun ki o ṣ'ara giri!

**ANDREWS YIO RAN Ọ LỌWỌ LATI TUN DI AKỌTUN NI ỌNA MẸTA**



1. Andrews oni-hiho suṣu yio ta ẹdọki rẹ ji—ile agbara ara rẹ.
2. Yio fọ inu rẹ mo jade, yio mu ara rẹ ṣe deede nipa tita awọn orike ara rẹ ji dada.
3. Yio jẹki inu rẹ ni adun, yio si mu oorun buruku ẹnu rẹ kuro.

**NISISIYI**
O le ri Andrews ra ni ọpọkuyọku, mimu lẹkan, awọn idi keekeeke . . . tabi awọn agolo ti a ti mọ dada.

LARỌ, LOSAN TABI LALẸ . . MU

# ANDREWS

LIVER SALT




FUN FIFỌ INU . . . . FUN OKUN ARA


Published by Allied newspapers Limited. Elephant House 21a, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited, 5/7, Apongbon Street, Lagos. Fun owo 'IROHIN YORUBA' odun kan EKO sile mejo ati kobo mejo (8/8d) ilu miran ni Nigeria ati Oke-Okun sile metala (13s) Olotu S. M. Ademuyiwa 2, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin